**ÒFIN TI MEMORIAL HERMANN SURGICAL HOSPITAL FIRST COLONY**

**ÀKỌLÉ ÒFIN:** Òfin Ìdíyelé àti Owó Gbígbà

**DÉÈTÌ ÀTẸ̀JÁDE:** 10/1/2018
**Ẹ̀YÀ:** 1

---

**ÈRÈDÍ ÒFIN:**

Òfin yìí fi ìdí àwọn ìlànà tó mọ́gbọ́n wá múlẹ̀ nípa gbígba àwọn àṣùwọ̀n aláìsan, títí dórí àwọn ìṣe tí Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony (“MHSHFC”) le ṣe tàbí bẹ àwọn aṣojú gbígbà ode lọ́wẹ̀.

**ÌWÒYE:**

Òfin yìí wà fún Memorial Hermann Surgical Hospital First Colony.

**GBÓLÓHÙN ÒFIN:**

1. Ó jẹ́ òfin MHSHFC láti lépa gbígba ìyókù owó aláìsàn láti ọwọ́ àwọn aláìsàn tó ní agbára láti sanwó fún àwọn iṣẹ́. Òfin yìí nṣàlàyé àwọn ìṣe tí MHSHFC le ṣe láti gba ìdíyelé ilé-ìwòsan àti/tàbí àwọn ìdíyelé míràn fún àwọn iṣẹ́ tí a pèsè fún àwọn aláìsàn MHSHFC. Òfin náà tún nṣàlàyé ìlànà àti gbèdéke àkókò tó níí̀ṣe pẹ̀lú àwọn iṣẹ́ owó gbígbà náà, àwọn ìgbésẹ̀ tí MHSHFC lè gbé tí wọn ò bá sanwó, àti àwọn ìgbésẹ̀ tí MHSHFC gbọ́dọ̀ gbé láti pinnu tí aláìsàn kan bá yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó.

2. Òfin yìí nṣàlàyé bí MHSHFC tí ń bá àwọn aláìsàn sọ̀rọ̀ nípa iyé owó tó yẹ fún àwọn iṣẹ́ tí MHSHFC ń pèsè.

3. MHSHFC yóò tiraka láti dá àwọn aláìsàn tó le yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó mọ̀.

4. Òfin yìí tún túmọ̀ irú ipò èyítí MHSHFC fi lè pa àṣùwọ̀n aláìsàn rẹ́ láì sanwó mọ́ àti ìlànà láti darí àti láti tọpinpin pípa àwọn ìyókù àwọn àṣùwọ̀n aláìsàn rẹ́.

5. MHSHFC kò níí kópa nínú Àwọn Ìṣe Àkànṣe Owó Gbígbà bí a ti kọsílẹ̀ nínú I.R.C. § 501(r) àti àwọn òfin tó báa wá.

6. Àwọn òfin àti ìlànà tí a kọ sílẹ̀ níhín ni a rò láti faramọ́ àwọn òfin àti ìṣesí ti ìpínlẹ̀ Texas, I.R.C. § 501(r) àti àwọn ìtọ́ni tó jọ ara wọn.

7. Àṣẹ olúborí láti pinnu bóyá MHSHFC ti gbé ìgbésẹ̀ tó dára láti pinnu àmúyẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó wà pẹ̀lú MHSHFC.

**ÀWỌN KÓKÓ Ọ̀RỌ̀ ÀTI ÌTUMỌ̀:**

1. *Ìbéèrè*: Ìbéèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní aláìsàn kan gbọ́dọ̀ fọwọ́sí.

2. *Àkókò Ìbéèrè:* Ní Àkókò Ìbéèrè, MHSHFC yóò gbà yóò sì ṣiṣẹ́ lórí ìbéèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. Àkókò Ìbéèrè bẹ̀rẹ̀ ní ọjọ́ tí a pèsè ìtọ́jú fún ẹnìkan ó sì parí ní ọjọ́ 240 lẹ́yìn déètì ìwé ìdíyelé àkọ́kọ́ fún ìtọ́jú náà.

3. *Ìparẹ́ Gbèsè*: Ìṣàtúnṣe sí àṣùwọ̀nalàìsàn fún iye owó tí a ríi wípé a kò le rí gbà mọ́, ṣùgbọ́n tí aláìsan náà ní agbára láti san ìyókù owó náà. Ìpinnu yìí dá lórí lílo àmúyẹ owó gbígbà tó fìdímúlẹ̀ a sì ńṣe é lẹ́yìn tí a ti díyelé àṣùwọ̀n kan nìkan tí a sì ti gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó dára fún owó gbígbà.

4. *Ìṣàtúnṣe Àdéhùn***:** Ìṣàtúnṣe kan tí a fi ránṣẹ́ sínu àṣùwọ̀n aláìsàn kan láti ṣàfihàn ìyàtọ̀ láàrín àpapọ̀ ìdíyelé aláìsàn ní òdiwọ̀n tó fìdímúlẹ̀ àti iye tí a ń retí láti san padà gangan láti ọ̀dọ̀ àwọn alàgàta olùsanwó sí àwọn ìṣedédé tó bá òfin mu tàbí àwọn ìṣètò àdéhùn.

5. *Àwọn Ìṣe Owó Gbígbà Ní Ọ̀nà Ọ̀tọ̀ (“ECAs”)* : Èyí ni àwọn ìṣe owó gbígbà tó nílò ìlànà iṣẹ́ òfin àti ti adájọ́, ó sì tún le kan àwọn iṣẹ́ míràn bíi títa gbèsè fún ẹlomíràn tàbí jíjábọ̀ àlàyé tó léwu sí àwọn aṣojú tàbí ilé-iṣẹ́ kírẹ́dìtì. **MHSHFC kò ṣàmúlò ECAs, bẹ́ẹ̀ni kò gba àwọn aṣojú owó gbígbà rẹ̀ láti ṣàmúlò ECAs.**

6. *Ìrànlọ́wọ́ Owó*: Ìrànlọ́wọ́ Owó túmọ̀ sí ìrànlọ́wọ́ tí MHSHFC ńfún àwọn aláìsàn tó yẹ fún àwọn amúyẹ owó kan pàtó àti àwọn ohun àmúyẹ míràn bí a ti túmọ̀ nínú FAP láti ràn wọ́n lọ́wọ́ láti gba àwọn ohun tó ṣe pàtàkì láti san fún àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtakì fún pàjáwìrì tàbí ti ìlera èyítí MHSHFC ń pèsè. Àwọn aláìsàn tó yẹ le kan àwọn aláìsàn tí kò ní ètò ìdójútòfò, àwọn aláìsàn tí owó-àpawọlé wọn kéré, àti àwọn aláìsàn tó ní ààbò díẹ̀ ṣùgbọ́n tí wọn kò le sanwó díẹ̀ tàbí gbogbo àwọn ìdíyelé ìlera wọn tó kù. Ìrànlọ́wọ́ owó kò níí̀ṣe pẹ̀lú àwọn owó àjẹmọ́nú àdéhùn lọ́dọ̀ àwọn ilé-iṣẹ́ adójútòfo àti ààbò ìlera alàgàta míràn.

7. *Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà (“PLS”)*: Ìsọníṣókí tó lọ tààràti FAP pẹ̀lú: (a) àlàyé díẹ̀ ti àwọn ohun àmúyẹ àti ìrànlọ́wọ́ tí a fúnni; (b) àtòkọti ojúlé wẹ́ẹ̀bù àti ibi àfojúrí tí wọ́n wà tí a ti le gba àwọn ìwé ìbèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó; (c) àwọn ìtọ́ni lórí bí a ti le gba ẹ̀dà oní-pépà ọ̀fẹ́ ti FAP; (d) àlàyé nípa kíkàn síni fún ìrànlọ́wọ́ pẹ̀lú ìlànà ìbéèrè; (e) wíwà nílẹ̀ fún ìtúmọ̀ èdè ti FAP àti àwọn ìwé míràn tó jọ ara wọn; àti (f) gbólóhùn ijẹ́rìísi pé àwọn aláìsàn tí a pinnu pé wọ́n yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ni a kò níí díyelé ju iye owó tí a ń bèrè fún pàjáwìrì tàbí àwọn iṣẹ́ ìtọ́jú ìlera tó ṣe pàtàkì.

8. *Àwọn Ìgbésẹ̀ Tó Ní Ìtumọ̀*: MHSHFC yóo gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó ní ìtumọ̀ láti pèsè àlàyé fún aláìsàn nípa FAP ti MHSHFC nípa fífún àwọn aláìsàn ní Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà ti FAP ní àkókò tí ó bá yá jùlọ. Ní àfikún, MHSHFC yóò gbé àwọn ìgbésẹ̀ wọ̀nyí láti wífún àwọn aláìsàn nípa FPA ti MHSHFC.

    a. *Àwọn Ìbéèrè Tí Kò Péye*: Tí aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí bá fa ìbéèrè tí kò péye kalẹ̀, lẹ́yìn náà MHSHFC yóò pèsè ìfitónilétí tí a fọwọ́kọ tí ń ṣàlàyé irú àfikún àlàyé tàbí ìwé àkọsílẹ̀ tó nílò.

    b. *Àwọn Ìbéèrè Tó Péye*: Tí aláìsàn náà àti/tàbí mọ̀lẹ́bí aláìsàn náà bá fa ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó tó péye kalẹ̀, MHSHFC yóò pèsè ìfitónilétí àfọwọ́kọ tí ń sọ nípa ìpinnu yálà aláìsàn náà yẹ fún Ìrànlọ́wọ́ Owó ní àkókò tó yẹ yóò sì sọ fún aláìsàn náà ní kíkọ nípa ìpinnu (pẹ̀lú, tó bá yẹ, ìranlọ́wọ́ fún èyítí aláìsàn náà yẹ fún) àti ìdí fún ìpinnu yìí. Ìfitónilétí yìí yóò tún pẹ̀lú iye ìdá nínú ọgọ́rùún Ìrànlọ́wọ́ Owó (fun àwọn ìbéèrè tí a fọwọ́sí) tàbí (àwọn) ìdí fún sísẹ́, àti iye owó sísan tí a ń retí lọ́wọ́ aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí tó bá wà. Aláìsàn náà àti/tàbí ẹbí yóò máa gba àkọsílẹ̀ owó ní àkókò àyẹ̀wò ti ìbéèrè tó péye.

    c. *Àwọn Àkọsílẹ̀ Owó Aláìsàn*: MHSHFC yóo fi oríṣìí àkọsílẹ̀ owó ránṣẹ́ tí ń ṣàlàyé àṣùwọ̀n aláìsàn àti iye tó yẹ láti san. Àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn yóo pẹ̀lú ìbéèrè kan wípé ó jẹ́ ojúṣe aláìsàn láti wí fún MHSHFC nípa wíwà nílẹ̀ èyíkéyìí ààbò iṣẹ́ ìdójútòfò ìlera kan, àkíyèsí FAP ti MHSHFC, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ kan láti béèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti àdírẹ́sì ojúlé-wẹ́ẹ̀bù níbití a ti le gba àwọn ìwé FAP.

    d. *Ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC*: Àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù MHSHFC yóò ṣe àgbéjáde àkíyèsí ní àwọn ibití ó ṣe pàtàkì pé Ìrànlọ́wọ́ Owó wà nílẹ̀, pẹ̀lú àlàyé ìlànà ìbéèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó. MHSHFC yóò ṣàgbéjáde FAP náà pẹ̀lú àtòkọ àwọn olùpèsè tó wà lábẹ́ àti àwọn tí kò sí lábẹ́ FAP, ìsọníṣókí èdè tó lọ tààrà, ìbèrè fún Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti Òfin Owó Gbígbà àti Ìdíyelé lórí ojúlé wẹ́ẹ̀bù ti MHSHFC: http://www.memorialhermannFirstColony.com/financial-assistance-program/. MHSHFC yóò ní àwọn ẹ̀dà oní-pépà ọ̀fẹ́ ti ìwé wọ̀nyí nílẹ̀ tí a bá béèrè ní ẹ̀ka iṣẹ́ pàjáwìrì àti àwọn ibi ìforúkọsílẹ̀.

**ÀWỌN ÀMÚYẸ ÀTÚNYẸ̀WÒ:**

1. *Bíbá Aláìsàn Sọ̀rọ̀*: Ní ìbẹ̀rẹ̀ iṣẹ́ owó àpawọlé, àwọn aláìsàn yóò gba ìbánisọ̀rọ̀ àfẹnusọ tàbí àkọsílẹ̀ nípa ìyókù owó wọn, àti àwọn ìrètí ìsanwó ti MHSHFC. Gbogbo ìbásọ̀rọ̀ pẹ̀lú aláìsàn yóò pẹ̀lú àkíyèsí nípa wíwà nílẹ̀ FAP, nọ́mbà ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ láti pè fún àfikún àlàyé, àti àdírésì ojúlé wẹ́ẹ̀bù níbi tí a ti le gba àwọn ẹ̀dà FAP àti àwọn ìwé tó jọ ara wọn. MHSHFC yóò fúnni ní ẹ̀dà Ìsọnìṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà ti FAP sí gbogbo aláìsàn.

a. Àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò ni a rétí kí wọ́n sowọ́pọ̀ pẹ̀lú MHSHFC nínú ìtiraka rẹ̀ láti dá àwọn orísun owó mọ̀ nípasẹ̀ àwọn ètò ìjọba ìpínlẹ̀ àti àpapọ̀ láti yanjú àwọn ìnáwó ìtọ́jú ìlera wọn. Àwọn aláìsàn tí kò ní ìdójútòfò yóò gba àkọsilẹ̀ owó oṣooṣù èyítí ń ṣàlàyé FAP náà, àti iye owó wọn tó kù títí da ọjọ́ 150 sí déètì iṣẹ́ náà. Tí aláìsàn kan bá kùnà láti wọ inú ètò ìsanwó kan lọ tàbí yanjú ìyókù gbèsè wọn MHSHFC yóò ṣàyẹ̀wò fífi àṣùwọ̀n náà ṣọwọ́ sí alàgàta ilé iṣẹ́ owó gbígbà míràn.

b. Àwọn aláìsàn tó ní ìdójútòfò ni a retí kí wọ́n ṣowọ́pọ̀ pẹ̀lú MHSHFC nínú ìgbìyànjú rẹ̀ láti gba àwọn ìsanwó láti ọ̀dọ̀ olùṣètò ìdójútòfò aláìsàn náà. Ó tún gbọ́dọ̀ yé aláìsàn pé nígbà tí MHSHFC bá díyelé olùṣètò ìdójútòfò aláìsàn náà ó jẹ́ ìlànà iṣẹ́ èyí kò sì ṣe ìmúkúrò ojúṣe owó ti aláìsàn láti sanwó fún àwọn iṣẹ́ tí MHSHFC pèsè. Nítorí náà, nígbà míràn MHSHFC yóò béèrè pé kí aláìsàn kan sowọ́pọ̀ pẹ̀lú olùṣètò ìdójútòfò rẹ̀ láti yanjú ìdádúró ìsanwó tàbí yanjú àwọn ìṣòro ìṣàkóso míràn èyítí ń dènà ìsanwó fún iṣẹ́ míràn. Kété tí MHSHFC bá ti gba owó fún àwọn iṣẹ́ tí a sì ti ṣàmúlò àwọn ìṣàtúnṣe àdéhùn tó dára sí àṣùwọ̀n náà aláìsàn náà yóò gba àkọsílẹ̀ owó oṣooṣù èyítí ń ṣàlàyé FAP àti iyókù owó tí ó tó ọjọ́ 120 lẹ́yìn ìsanwó olùṣètò ìdójútòfò. Tí aláìsàn kan bá kùnà láti wọ inú ètò ìsanwó kan lọ tàbí yanjú ìyókù gbèsè wọn MHSHFC yóò ṣàyẹ̀wò fífi àṣùwọ̀n náà ṣọwọ́ sí alàgàta ilé iṣẹowó gbígbà míràn.

2. *Ìrànlọ́wọ́ Owó*: Ó jẹ́ ìṣe MHSHFc láti ran àwọn aláìsàn lọ́wọ́ láti rí ìsanpadà owó gbà láti ọ̀dọ̀ àwọn alàgàta míràn. A ó pèsè ìmọ̀ràn ìṣúná owó láti ran àwọn aláìsàn lọ́wọ́ láti mọ àwọn ètò ààbò ìtọ́jú ìlera ti ìjọba ìpínlẹ̀ tàbí àpapọ̀ èyí tó le wà nílẹ̀ fún wọn, àti láti pinnu àmúyẹ lábẹ́ FAP náà. Ìṣẹ́ owó gbígbà ni a ó dá dúró fún ìgbà díẹ̀ títí di ìgbà tí a bá rí àbájáde ìpinnu wọ̀nyí, ṣùgbọ́n àwọn àkọsílẹ̀ owó aláìsàn ni a ó máa fìránṣẹ́. Fún Ìrànlọ́wọ́ Owó nípasẹ̀ MHSHFC, àwọn àmúyẹ tí a ń lò láti ṣírò iye ẹ̀dínwó, àwọn ìgbésẹ̀ tí MHSHFC yóò gbé láti polongo FAP náà láàrín àdúgbò tí MHSHFC ńṣiṣẹ́ sìn, ìlànà tí MHSHFC lò láti pinnu ìmúyẹ Ìrànlọ́wọ́ Owó, àti ìlànà ìbéèrè náà ni a ṣàlàyé ní ẹ̀kúnrẹ́rẹ́ nínú **MHSHFC** **[Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó]()**

3. *Àwọn Ètò Ìsanwó*: MHSHFC ń fún àwọn aláisàn tó ní ìṣòro láti sanwó fún ìdíyelé wọn ní àwọn ètò ìsanwó tó gùn, tí kò sì ní owó àsanlé. Àwọn aláìsàn le ṣètò ìsanwó nípa bíbá àwọn aláṣẹ ìforúkọsílẹ̀ sọ̀rọ̀ ní déètì iṣẹ́, tàbí bíbá olùdámọ̀ràn ètò-ìṣúná sọ̀rọ̀ nígbàkugbà ṣáájú tàbí lẹ́yìn déètì ti iṣẹ́. A ó bèrè lọ́wọ́ àwọn aláìsàn láti sanwó oṣooṣù ó kéré jù láti tọ́jú ètò ìsanwó tí ń ṣiṣẹ́. Tí aláìsàn kan bá kùnà láti sanwó bí a ti ṣètò a ó rí aláìsàn náà bíi ọ̀daràn lórí ìlérí tí wọ́n ṣe láti sanwó fún gbèsè inú àṣùwọ̀n wọn. A ó gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó dára láti tún fi ìdí ètò ìsanwó aláìsàn náà múlẹ̀ nípa títẹ̀lé ìsanwó ọ̀daràn àkọ́kọ́. Tí aláìsàn kan bá kùnà láti tún fi ìdí ètò ìsanwó kan múlẹ̀ àti/tàbí tí ó di ọ̀daràn fún ìgbà ìkejì MHSHFC yóò fi àṣùwọ̀n náà ṣọwọ́ sí alàgàta ilé iṣẹ́ owó gbígbà. Kété tí a bá fi ṣọwọ́ sí alàgàta ilé iṣẹ́ owó gbígbà aláìsàn náà yóò ní láti ṣiṣẹ́ papọ̀ tààrà pẹ̀lú alàgàta ilé iṣẹ́ owó náà láti yanjú gbesè wọn tó kù. Aláìsàn náà kò níí yẹ láti ṣètò ìsanwó míràn pẹ̀lú MHSHFC.

4. *Àwọn Ìṣẹ́ Owó Gbígbà Tí A Kò Bá Sanwó:* Tó bá wáyé pé ẹnìkan kò sanwó, a ó ṣàmúlo oríṣìí iṣẹ́ owó gbígbà èyí tó dá lórí ìyókù owó, gbèsè àsanpadà alàgàta olùsanwó, àmúyẹ aláìsàn fún owó ìjọba tàbí Ìrànlọ́wọ́ Owó, ìsowọ́pọ̀ aláìsàn, ìtàn ìsanwó tàbí gbèsè, àti/tàbí àìle rí aláìsàn náà. Àwọn iṣẹ́ owó gbígbà le pẹ̀lú ẹ̀bẹ̀ sísẹ́ alàgàta olùsanwó; ìbánisọ̀rọ̀ láti ṣàbẹ̀wò pẹ̀lú alàgàta olùsanwó; àwọn àkọ́ọ́lẹ̀ owó, lẹ́tà, àti àwọn ìpè lórí ẹ̀rọ ìbánisọ̀rọ̀ sí aláìsàn náà tí ó ń fúnni ní Ìrànlọ́wọ́ Owó ati/tàbí bíbéèrè ìsanwó; àti ìfitónilétí ìkẹyìnsí aláìsàn náà tàbí olùfọwọ́sọ̀yà pé àṣùwọ̀n náà ti dáràn ó sì yẹ kí a fifún ile iṣẹ́ owó gbígbà tí kò gbọ́dọ̀ yá ju ọjọ́ 120 lọ láti déètì àkọ́ọ́lẹ̀ owó àkọ́kọ́ tí ó nwí fún aláìsàn náà ti iye owó tí aláìsàn náà jẹ, àyàfi ti aláìsàn náà bá ti jẹ̀bi lórí ètò ìsanwó tí a faramọ́ nípa nkan 3 lókè. A tún le bẹ̀rẹ̀ ìṣe òfin nípasẹ̀ MHSHFC sí alàgàta tó yẹ (gbèsèalàgàta) fún ìsanwó ọ̀daràn ti àṣùwọ̀n náà.

5. *Gbèsè àìlè san padà*: A le pa àwọn àṣùwọ̀n kan rẹ́ sí gbèsè tí a kò le san padà lẹ́yìn tí a ti díyelé àṣùwọ̀n náà pátápátá sí (àwọn) alàgàta olùsanwó àti sí aláìsàn/olùfọwọ́sọ̀yà náà, ìdíyelé tí a fìdí rẹ̀ múlẹ̀ àti àwọn ìbánisọ̀rọ̀ àbẹ̀wò ti wáyé, a sì tí gbé àwọn ìgbésẹ̀ tó péye láti sọ fún aláìsàn náà nípa wíwà nílẹ̀ ti Ìrànlọ́wọ́ Owó, àkókò ìsanwó ti dópin, a sì ti pinnu wípé a kò le rí owó náà gbà padà mọ́.

6. *Àwọn Ìṣe Owó Gbígbà Ti Òde*: Láti ṣàrídájú wípé àwọn àṣùwọ̀n tó lẹ́tọ̀ọ́ nìkan ni a parẹ́ sí gbèsè tí a kò le rígba mọ́, àti wípé lẹ́yìn tí a ti gbé àwọn ìgbésẹ̀ ìdíyelé àti owó gbígbà nìkan, pẹ̀lú ìtọ́kasí tó dára sí ilé-iṣẹ́ òde kan fún owó gbígbà, ẹgbẹ́ Iṣẹ́ Oníbàárà yóò ṣàyẹ̀wò ìparẹ́ àwọn gbèsè tí a kò le rígbà fún ìfọwọ́sí. Ṣíṣeàmúlò àwọn àmúyẹ owó gbígbà tó fìdímúlẹ̀ àti òdíwọ̀n àṣẹ ìfagilé tí a fọwọ́sí (wo MHSHFC **[Òfin Ìṣàtúnṣe Iṣẹ́ Ìṣòwò Aláìsàn]**), Adarí Ilé-iṣẹ́ Ìṣòwò le yálà fọwọ́sí ìfagilé tàbí gba Ọ̀gá Ètò-ìṣúná Àgbà Ilé-ìwòsàn nímọ̀ràn nìpa ìṣe tí ó yẹ.  Àwọn àṣùwọ̀n ni a tún le fi ṣọwọ́ ní tàárà sí ilé-iṣẹ́ òde fún owó gbígbà nípasẹ̀ ìlànà ìṣírò owó aláìsàn náà, èyí tó dá lórí olùsanwó to fẹsẹ̀múlẹ̀, ìyókù owó, àti àwọn òdiwọ̀n iṣẹ́ ìsanwó.

7. *Ìmúṣiṣẹ́*: Ó jẹ́ ojúṣe Ilé-iṣẹ́ Ìṣòwò Aláìsàn MHSHFC àti Ilé-iṣẹ́ Ìdíyelé Àpapọ̀ (CBO) láti ṣàmúlò òfin yìí àti láti mú àwọn ìlànà ìṣiṣẹ́ pàtó ti ẹ̀ka-iṣẹ́ dàgbà.

**<u>ÀWỌN IBI ÌTỌ́KASÍ:</u>**

A. Òfin Ìfiṣọwọ́ Aláìsàn (EMTALA àti Ìfaramọ́ Òfin Ìfiṣọwọ́ Texas)
B. Òfin Ìrànlọ́wọ́ Owó
C. Ìsọníṣókí Èdè Tó Lọ Tààrà Ti Ìrànlọ́wọ́ Owó
D. Ìbéèrè Ìrànlọ́wọ́ Owó